UK Health Security Agency

NHS CARE



# Ìtọ́sọ́nà kan sí ètò gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19 ti ìgbà ìrúwé 2025

**Àwọn ènìyàn tí ọjọ́-orí wọn jẹ́ 75 àti jùbẹ́ẹ̀lọ, àwọn olùgbé ní ilé ìtọ́jú àwọn àgbàlagbà, àti àwọn ọmọ ọdún 6 sí òkè t'óní ètò àjẹsára tí kò l'ágbára yóò gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ààrùn kòkòrò korona (COVID-19) ní ìgbà ìrúwé yìí.**

## Tani yóò gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ti ìgbà ìrúwé?

COVID-19 le pípọ̀ nínú àwọn ènìyàn tó dàgbà àti nínú àwọn ènìyàn pẹ̀lú pàtó ipò àìlera kan. Fún àwọn èrèdí wọnyi, a fún àwọn ènìyàn tí ọjọ́-orí wọn jẹ́ 75 àti jùbẹ́ẹ̀lọ, àwọn tó wà ní ilé ìtọ́jú, àti àwọn ọmọ osù 6 àti jùbẹ́ẹ̀lọ t'óní etò àjẹsára tí kò l'ágbára ni abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19 ti ìgbà ìrúwé.

## Àkókò abẹ́rẹ́ àjẹsára ìgbà ìrúwé.

O gbọdọ̀ gba àkókò ìpàdé kan láàrin osù Kẹrin àti Kẹfà, tí á ó sì kọ́kọ́ pe àwọn tóní ewu gíga wọlé. A ó pè ọ lati gba àlékún rẹ ní bíi osù 6 lẹ́yìn abẹ́rẹ́ tó gbẹ̀yìn sùgbọ́n, o le tètè gbàa ní osù 3.

Bí ó bà máa pé ọdún 75 lọ́jọ́ orí láàrin osù Kẹ̀rin àti Ìkẹfà, o kò nílò láti dúró títí ọjọ́-ìbí rẹ, o lè kópa nígbàtí wọ́n bá pè ọ́ fún etò abẹ́rẹ́ àjẹsára.

## Abẹ́rẹ́ àjẹsára wo ni o máa gbà?

A ó fún ọ ní àlékún abẹ́rẹ́ àjẹsára tí Pfizer, Moderna tàbí Sanofi ṣe ti orílẹ̀-èdè UK si fọwọ́sí. Àwọn abẹ́rẹ́ wọnyi ti dójú ìwọ̀n níwọ̀n bí láti igba abẹ́rẹ́ àjẹsára àkọ́kọ́ tí a sì fojúsun orísìí COVID-19 mìíràn. Awọn àlékún abẹ́rẹ́ àjẹsára tó ti dojuiwọn wọnyi ńmu kí ààbò gbèrú sí dáradára, o si tun ńpèsè àwọn àjẹsára ní àwọn ìpele gíga díẹ̀ tako àwọn ọwọ́jà COVID-19 (Omicron) tó sẹ̀ṣẹ̀ wáyé lọ.

Gẹ́gẹ́bí a kò ti le sọ irú àwọn orísìí COVID-19 tí yóò ma ràn káàkiri ní àkókò ìrúwé àti ooru yìí, Ìgbìmọ̀ Àpapọ̀ lórí Gbigba Abẹ́rẹ́ Àjẹsára àti Abẹ́rẹ́ Àjẹsára (JCVI) ti fẹnukò pé àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára tí a lòkù ní ọ̀sẹ̀ àsekágbá ètò ìrúwé ọdún 2024 le jẹ́ lílò.

> Jọ̀wọ́ gba abẹ́rẹ́ àjẹsára tí a bá fún ọ ní kíákíá bí ó ti seéṣe fún ọ – a ó fún ọ ni abẹ́rẹ́ àjẹsára tó yẹ ní àkókò tó yẹ.



## Tani kò le gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ìgbà ìrúwé

Àwọn ènìyàn díẹ̀ ló wà tí kò gbọ́dọ̀ gba abẹ́rẹ́ ìrúwé yìí. Bí o bá ti ní àdẹ̀hìnbọ̀ tí o le sí abẹ́rẹ́ àjẹsára tó gbà sẹ́yìn o gbọ́dọ̀ bá dókítà rẹ sọ ẹ̀yí.

## Àwọn ìdíjú

**Àwọn ìdíjú tó wọ́pọ̀:** Gẹ́gẹ́bí abẹ́rẹ́ tó ti gbà sẹ́yìn, àwọn ìdíjú tó wọ́pọ̀ papọ̀ mọ́ ti gbogbo abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID_19, pẹ̀lú àwọn àpapọ̀ abẹ́rẹ́ àjẹsára tí a lò ní àkókò òtútù yìí, tí ó pẹ̀lú:

- níní ìnira kan, ìmọ̀lára ara wíwo àti ara rírọ̀ ní apá níbití o ti gba àbẹ́rẹ́ – ẹ̀yí le ṣeéṣe kó burú tó bíi ọjọ́ 1 sí 2 lẹ́yìn abẹ́rẹ́ àjẹsára náà
- ìmọ̀lára rírẹ̀
- orí fífọ́
- ara ríro gbogbogbo tàbí ààmì àìsàn ọ̀fìnkìn tí kò le

O le sinmi kí o sì lo òògùn paracetamol (tẹ̀lé ìmọ̀ràn abẹ́rẹ́ nínú àpamọ́ náà) láti ràn ọ́ lọ́wọ́ kí o gbádùn dáradára.

Àwọn ìdíjú tó ńtẹ̀lé gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára kìí sáábà pẹ́ tó ọ̀sẹ̀ kan. Bí àwọn ààmì àìsàn rẹ bá fẹ́ burú tàbí bí àyà bá ńfò ọ́, o le pe NHS 111 tàbí fún àtẹ̀jíṣẹ́ lo 18001 111.

O tun le jábọ̀ àwọn ìdíjú abẹ́rẹ́ àjẹsára àti òògun tí o furasí. Jọwọ wo alaye ikansini fun eto naa ni ẹyin iwepelebe yii.

**Àwọn ìdíjú to le:** Àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ọkàn wíwú (tí à ńpè ní myocarditis àbí pericarditis) ni wọ́n ti jábọ̀ níwọ̀nba lẹ́yìn irú àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19 Pfizer àti Moderna. Àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ wọ̀nyí ni a ti ń sábà rí nínú àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin àti láàrin ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọjọ́ gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn tó ṣẹlẹ̀ siì ti ṣe dáradára wọ́n sì ti gbádùn kíákíá ní àyọrísí ìsinmi àti àwọn ìtọ́jú pẹ́pẹ́pẹ́. O gbọ́dọ̀ wá ìmọ̀ràn ìlera ní kíákíá bí, lẹ́yìn gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára, o ní ìrírí:

- ìrora àyà
- èémí kúkúrú
- ìmọ̀lára níní yíyáralu ọkàn, àìfọkànbalẹ̀ tàbí ọkan lílù pìpì

Bí o bá ní àwọn ìdíjú líle lẹ́yìn abẹ́rẹ́ àjẹsára tó gbà sẹ́yìn a le gbà ọ́ nímọ̀ràn pé kí o yàgò fún tàbí dá gbígbà abẹ́rẹ́ àjẹsára mìíràn duro. O gbọ́dọ̀ jíròrò èyí pẹ̀lú dókítà tàbí akọ́ṣẹ́mọ̀ṣẹ́ rẹ. Jọ̀wọ́ wo ojú-ewé tó wà ní ẹ́yìn ìwé pélébé náà lórí bí o ṣe le jábọ̀ àwọn ìdíjú.

## Kíni ó yẹ kí o ṣe bí o kò bá gbádùn ní ọjọ́ ìpàdé rẹ?

Bí ara rẹ kò bá yá, dúró títí ó fi badà bọ̀ sípò láti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára rẹ. O kò gbọdọ̀ lọ síbi ìpàdé kan bí o bá ní ibà tàbí rò wípé o le kó àrùn ran àwọn mìíràn.

## Ǹjẹ́ o le sì le ní COVID-19 lẹ́yìn gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára?

Abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19 yóò dín ààyè níní àìsàn líle kù láti ọ̀dọ̀ COVID-19 ní àkókò ìrúwé àti ooru yìí. Ó le lo àwọn ọjọ́ díẹ̀ kí ara rẹ tó ní àwọn àlékún ààbò láti ọ̀dọ̀ àfikún abẹ́rẹ́ àjẹsára. Bíi gbogbo òògùn, kòsí abẹ́rẹ́ àjẹsára tó péye pátápátá. Àwọn ènìyàn kọ̀ọkan tun le ní COVID-19 biotilẹjẹpe wọ́n gba abẹ́rẹ́ àjẹsára, sùgbọ́n èyíkèyí àrànmọ́ kò gbọ́dọ̀ nira jù.

## Bí o kò bá tíì gba gbogbo abẹ́rẹ́ àjẹsára rẹ

Bi o ba yẹ sugbọn o ko tii gba abẹrẹ ajẹsara saaju tabi ti pa abẹrẹ kan jẹ tẹlẹ, o si gbọdọ gba abẹrẹ kan ni igba iruwe yii. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn kò nílò àlékún awọn abẹ́rẹ́ láti dípò àwọn èyítí o ti pajẹ. Bí o bá ní ètò àjẹsára tí kò l'ágbára dókítà rẹ le gbà ọ́ dámọ̀ràn àlékún abẹ́rẹ́ fún osù mẹ́ta lẹ́yìn tí o bá ti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ìgbà ìrúwé.

## Ǹjẹ́ màá nílò láti dúró lẹ́yìn abẹ́rẹ́ àjẹsára mi?

Bí o bá ní ìtàn àìbáramu kan, tàbí bí o bá ní àtunbọ̀tán kan lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ lẹ́yìn abẹ́rẹ́ tí o ti gbà, a le gbà ọ́ nímọ̀ràn láti dúró fún ìṣẹ́jú 15 lẹ́yìn abẹ́rẹ́ àjẹsára náà. Jọ̀wọ́ ríi dájú wípé o sọ fún alábẹ́rẹ́ àjẹsára.

## Ìwífún síwájú síi

O le ka àwọn ìtọ́sọ́nà COVID-19 nisalẹ fun ìwífún síwájú síi

Ṣe àbẹ̀wò sí **eto abẹrẹ ajẹsara coronavirus** ni NHS.UK.

Ìwé ìwífún lórí ohun **tí o nretí lẹ́yìn gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára** wà ní àrọ́wọ́tó láti gbà sílẹ̀ lórí ẹrọ.

Kà nípa àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára tí Pfizer fun**awọn agba ati ọdọ ti ọjọ-ori wọn jẹ ọdun 12 soke** fun **awọn ọmọde ti wọn jẹ ọdun 5 si 11 l'ọjọ ori** ati **awọn ọmọde to wa ni osu 6 si ọdun 4 l'ọjọ ori** ati  abẹrẹ ajẹsara Moderna **fun awọn agba** fún àlàyé síi lórí abẹ́rẹ́ àjẹsára rẹ, pẹ̀lú àwọn ìdíjú tó seéṣe.

ojú-ewé káádì Yellow (Yellow Card) tàbí nípa pípe 0800 731 6789 (agogo 9 òwúrọ̀ si 5 ìrọ̀lẹ́ Ọjọ́ Ajé sí Ẹtì) tàbí nípa gbígba ápùù Yellow Card sílẹ̀ sórí Apuu

**www.mhra.gov.uk/yellowcard**

A ó pè ọ lati gba àlékún abẹ́rẹ́ àjẹsára rẹ, GP rẹ le fún ọ ní abẹ́rẹ́ àjẹsára tàbí o le forukọsilẹ nípa lílo **ápùù NHS**.

Download on the App Store | GET IT ON Google Play

Tàbí ṣe abẹwo si **www.nhs.uk/vaccine-walk-in** láti s'awarí gbọ̀ngán gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára tó sunmọ ọ jùlọ.



© Crown copyright 2025. 1p 750k MAR 2025 (APS). Product code: C25SP2YO Yoruba. UK Health Security Agency gateway number 20241123. The leaflet can be ordered using the above product code, or downloaded from: **www.healthpublications.gov.uk**, by calling: 0300 123 1002 (lines are open 8am to 6pm Monday to Friday).

There are also translated versions of this leaflet in Albanian, Arabic, Bengali, Bulgarian, Chinese (simplified), Chinese (traditional, Cantonese), Estonian, Farsi, French, Greek, Gujarati, Hindi, Italian, Latvian, Lithuanian, Pashto, Polish, Portuguese, Punjabi, Romanian, Romany, Russian, Somali, Spanish, Tagalog, Tetum, Tigrinya, Turkish, Twi, Ukrainian, Urdu, Yiddish and Yoruba. You can also download an audio version and BSL video, and order a braille and large print copy.